# Sọ́ọ̀lù Ọba

KÁÀDÌ BÍBÉLÌ 41

SỌ́Ọ̀LÙ ỌBA











## SỌ́Ọ̀LÙ ỌBA

**ÌSỌFÚNNI ṢÓKÍ** Òun ni ọba tó kọ́kọ́ jẹ ní Ísírẹ́lì. Nígbà tí Sọ́ọ̀lù kọ́kọ́ di ọba, ó nírẹ̀lẹ̀, ó sì mọ̀wọ̀n ara ẹ̀. Àmọ́ nígbà tó yá, ó bẹ̀rẹ̀ sí í gbéraga, Jèhófà sì kọ̀ ọ́ lọ́ba. Sọ́ọ̀lù bẹ̀rẹ̀ sí í wá Dáfídì tó ti di akọgun kiri, ó fẹ́ pa á. Àmọ́ Jèhófà dáàbò bo Dáfídì, Sọ́ọ̀lù sì pa dà kú nígbà kan tó lọ bá àwọn Filísínì jagun.—1 Sámúẹ́lì 31:1-4.

### ÌBÉÈRÈ

**A.** Èwo nínú àwọn ọmọ Sọ́ọ̀lù ló di ọ̀rẹ́ Dáfídì tímọ́tímọ́?—1 Sámúẹ́lì 18:1.

**B.** Wòlíì Sámúẹ́lì sọ fún Sọ́ọ̀lù pé: “_____ sàn ju ẹbọ lọ.”—1 Sámúẹ́lì 15:22.

**D.** Béẹ̀ ni àbí béẹ̀ kọ́? Ọ̀lẹ ni Sọ́ọ̀lù, kò lágbára. —2 Sámúẹ́lì 1:23.

### ÌDÁHÙN

**A.** Jónátánì.

**B.** Ṣíṣègbọràn.

**D.** Bẹ́ẹ̀ kọ́. Wọ́n fi Sọ́ọ̀lù wé ẹyẹ idì tó ń yára fò àti kìnnìún tó lágbára.




www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania